## Mo gba àjẹsára ikọ́ féwe (TB) (BCG) ní orílẹ̀-èdè mi. Ṣé mo sì lè ní ikọ́ féwe (TB)?




Àwọn ènìyàn tí wọ́n gba àjẹsára ikọ́ féwe (TB) ṣì lè ní ikọ́ féwe (TB).

Ìdáábòbò àjẹsára ikọ́ féwe (TB) **yóò kúrò pẹ̀lú ìrékọjá àkókò**

Kódà bí o bá ní àjẹsára náà, àyẹ̀wò ẹ̀jẹ̀ tó ní àmì rere túmọ̀ sí pé o ní ikọ́ féwe tó pamọ́ (LTBI).

Lílo **òògùn ikọ́ féwe tó pamọ́ (LTBI)** yóò **dáàbò bò ọ́ lọ́wọ́ ikọ́ féwe (TB) tí ń ṣiṣẹ́ lọ́wọ́**.

## Ṣé níní ikọ́ féwe tó pamọ́ (LTBI) yóò ṣe ìdádúró ètò ìforúkọsílẹ̀ ìwọlé mi?

Lílo òògùn fún ikọ́ féwe tó pamọ́ (LTBI) yóò **RÁRÁ** fa ìrẹ̀wẹ̀sì ètò ìforúkọsílẹ̀ rẹ.

Dókítà ìwọlé rẹ yóò jẹ́ kí ẹ̀ka ètò ìlera rẹ mọ̀ pé o ní ikọ́ féwe tó pamọ́ (LTBI).

Ẹ̀ka ètò ìlera ìbílẹ̀ náà lè kàn sí ọ láti pèsè àtìlẹ́yìn.

Tí o bá nílò ìrànlọ́wọ́ láti wá dókítà kan tó lè bá ẹ ra òògùn fún ikọ́ féwe tó pamọ́ (LTBI), pe ẹ̀ka ètò ìlera agbègbè rẹ:

**Agbègbè:** ____________________

**Nọ́mbà fóònù:** ____________________

Àjàkálẹ̀ Àrùn Àkóràn, Ìdènà àti Ìṣàkóso
PO Box 64975, St. Paul, MN 55164
651-201-5414 or 1-877-676-5414
www.health.state.mn.us

1/2024

# Kí ni níní ikọ́ féwe tó pamọ́ (LTBI) túmọ̀ sí fún mi?



**O lè ṣe ìtọ́jú ikọ́ féwe tó pamọ́ (LTBI) àti dá ìwọ àti àwọn olólùfẹ́ rẹ dúró láti ṣàìsàn.**

DEPARTMENT OF HEALTH

Wọ́n lo pẹ̀lú ìyọ̀da láti ọwọ́ Àjọ Àwọn adarí Ikọ́ Féwe California.

## Kí ni ikọ́ féwe tó pamọ́ (LTBI)? Báwo ni mo ṣe ko?

Ikọ́ féwe tó pamọ́ (LTBI) jẹ́ àkóràn pẹ̀lú àwọn kòkòrò àìfojúrí ti ikọ́ féwe (TB) tó wà ní pamọ́ (tàbí ń sùn) nínú ara rẹ.

O ní ikọ́ féwe tó pamọ́ (LTBI) láti ara **pínpín atẹ́gùn** pẹ̀lú ẹnìkan tó ní ikọ́ féwe (TB) tí ń ṣiṣẹ́ lọ́wọ́

O sì lè ní ikọ́ féwe tó pamọ́ (LTBI) kódà bí o bá ní àjẹsára ikọ́ féwe (TB).

## Àwọn ìyàtọ̀ púpọ̀ ló wà láàrín ikọ́ féwe tó pamọ́ (LTBI) àti ikọ́ féwe (TB) tí ń ṣiṣẹ́ lọ́wọ́:

| Ẹni tó ní **ikọ́ féwe tó pamọ́ (LTBI)**: | Ẹni tó ní **ikọ́ féwe (TB) tí ń ṣiṣẹ́ lọ́wọ́**: |
|---|---|
| Kò ní ṣàìsàn | Ó lè ṣàìsàn |
| Ó ní àwòrán àyà tó ṣe déédé. | Ó lè ní àwòrán àyà tí kò ṣe déédé. |
| **Kò le ṣe àtànkálẹ̀ kòkòrò àìfojúrí ikọ́ féwe (TB)** sí àwọn elòmìràn | **Lè ṣe àtànkálẹ̀ kòkòrò àìfojúrí ikọ́ féwe (TB)** sí àwọn elòmìràn |
| Ìtọ́jú lè dènà ikọ́ féwe (TB) tí ń ṣiṣẹ́ lọ́wọ́ | Ìtọ́jú lè ṣe ìwòsàn ikọ́ féwe (TB) tí ń ṣiṣẹ́ lọ́wọ́ |
| Ìtọ́jú kéré **(oṣù méta sí mẹ́rin)** ó sì rọrùn | Ìtọ́jú gùn **(oṣù mẹ́fà sí 12 tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ)** |

## Kí ló dé tí mo fi gbọ́dọ̀ lo oògùn fún ikọ́ féwe tó pamọ́ (LTBI)?

Tí o kò bá lo òògùn fún ikọ́ féwe tó pamọ́ (LTBI), ó lè di ikọ́ féwe (TB) tí ń ṣiṣẹ́ lọ́wọ́.




Ikọ́ féwe (TB) tí ń ṣiṣẹ́ lọ́wọ́ jẹ́ **àìsàn tó lágbára** tó lè mú ọ ṣàìsàn gidi.



**Ìdaji** àwọn ènìyàn tí wọ́n ní ikọ́ féwe (TB) tí ń ṣiṣẹ́ lọ́wọ́ **ni wọ́n gbé lọ sí ilé ìwòsàn.**

**Ìdá 5**

ti àwọn ènìyàn tó ní ikọ́ féwe (TB) tí ń ṣiṣẹ́ lọ́wọ́ **kú láti ọwọ́ àìsàn náà**

## Báwo ni mo ṣe lè rí òògùn fún ikọ́ féwe tó pamọ́ (LTBI)?

**Béèrè lọ́wọ́ dókítà ìwọlé náà bóyá wọ́n lè** béèrè fún oògùn náà fún ọ.

Tí wọn kò bá lè ṣe é, **lọ sọ́dọ̀ dókítà déédé rẹ kí o sì sọ fún wọn pé kí wọ́n béèrè fún òògùn náà** fún ọ. Mú ìwé àyẹ̀wò ẹ̀jẹ̀ rẹ wá pẹ̀lú rẹ.

O tún lè kàn sí ẹ̀ka ètò ìlera ìbílẹ̀ rẹ láti tọ́ka rẹ sí ilé ìwòsàn fún ìtọ́jú.

**Tí o kò bá lo oògùn náà, o ní ọ̀kan nínú mẹ́wàá àfààní** pé ikọ́ féwe tó pamọ́ (LTBI) rẹ yóò di ikọ́ féwe (TB) tí ń ṣiṣẹ́ lọ́wọ́.

**Dáàbò bo ara rẹ lọ́wọ́ nínì ikọ́ féwe (TB) tí ń ṣiṣẹ́ lọ́wọ́ àti ṣíṣe àtànkálẹ̀ rẹ sí àwọn olólùfẹ́ rẹ.**